# IBẸRẸ IDAJỌ LORI IGIPTI

## Ẹksodu 7:14-25; 8:1-19

### ẸKỌ 53 -- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ohun ẹ̀ru ni lati ṣubu si ọwọ́ Ọlọrun alãye" (Heberu 10:31).**

**Israẹli Rẹwẹsi**

Nigba ti Mose ati Aaroni beere lọwọ Farao pe ki o jẹ ki Israẹli lọ ni irin ọjọ mẹta si ijù lati rubọ si Ọlọrun, Farao kọ̀ delẹ lati gba ẹ̀bẹ̀ wọn o si tun mú wọn ṣiṣẹ ti o le ju ti atẹyinwa lọ. Awọn Ọmọ Israẹli ti le banujẹ pe a tilẹ mu ọ̀rọ yii wá siwaju Farao ràrá, nitori wọn jiya pupọ si i ju ti atẹyinwa lọ. Wọn le maa wi ninu ọkàn wọn pe bi Ọlọrun ba n fẹ lati gbà wọn, ki ni ṣe ti kò ṣe é lẹsẹkẹsẹ. Bi Ọlọrun ba ni agbara lati ṣe ohun gbogbo ki ni ṣe ti ko mu ki Farao fẹ lati jẹ ki awọn eniyan naa lọ? tabi bi Farao ba ṣe ori kunkun sibẹ, ki ni ṣe ti kò mu un kuro lori itẹ ki O si sọ ọ di alailagbara?

Ṣugbọn Ọlọrun ti sọ fun Mose pe ọ̀ran naa ju pe ki a kan dá awọn Ọmọ Israẹli silẹ lasan lọ. Awọn ara Egipti yoo mọ̀ nipa ogo Ọlọrun tootọ nigba ti O ba ti ṣe gbogbo eyi ti yoo ṣe si wọn tán. Awọn Ọmọ Israẹli si n bọ wa gba ibukun ti o pọ pupọ ju bẹẹ lọ bi wọn ba duro de akoko Ọlọrun lati mu wọn jade.

**Suuru Gba Èrè**

Nigba miiran a maa n rẹ̀wẹsi nigba ti a ba n duro de imuṣẹ awọn ileri Ọlọrun, ṣugbọn irẹwẹsi ki i ṣe ohun ti o dùn mọ́ Ọlọrun rara. O mọ eyi ti o dara ju lọ, bi a ba si le duro de akoko Ọlọrun, Oun yoo rọjọ ibukun sori wa. A ri apẹẹrẹ eyi ninu igbesi-ayé Elijah. Nigba ti ayaba Jesebẹli n lepa rẹ̀ lati pa a nitori pipa ti o pa awọn aadọta le ni irinwo (450) wolii Baali. Elijah sá lọ si ijù o si beere pe ki Ọlọrun jẹ ki oun kú. O rò pé oun nikan ni o kù ti o fẹran Ọlọrun, ki ni ṣe ti oun yoo fi duro sibẹ si i ninu ayé? Ṣugbọn Ọlọrun ni ohun ti o ju bẹẹ lọ ni ipamọ fun un. Ni akọkọ, iṣẹ wà fun un lati ṣe: Ọlọrun ran an lati lọ fi ororo yan ọba titun kan lori Siria, ati ọba miiran fun Israẹli, ati wolii miran lati rọpo rẹ̀. Lẹyin eyi ni ipalarada ologo ṣẹlẹ fun Elijah, o lọ si Ọrun ninu kẹkẹ iná, kò si ni lati kú. Bi o ba ti gba ọna ti rẹ̀ ti o si kú ni akoko ti o ti dabi ẹni pe kò si ireti mọ́, oun i ba padanu igoke re Ọrun ti aṣẹgun eyi ti o jẹ pe kiki ẹni kan ṣoṣo ṣaaju rẹ̀, Enọku ni o ti ni iru iriri bẹẹ. Wo iru ibukun ti a n ri gbà nigba ti a ba duro de akoko Ọlọrun!

**Ọkan ti o Sele nipa Kíkọ Ọlọrun**

Ọlọrun fi gbogbo anfaani silẹ fun Farao lati ronupiwada ipinnu rẹ̀ akọkọ. Bi Oluwa ba ti n tẹnu mọ ọrọ i sọ fun ẹlẹṣẹ tó ti o si n kọ̀ lati gbọran, bẹẹ ni ọkàn rẹ yoo maa sele si i. "ẸNITI a ba mbawi ti o wà ọrùn kì, yio parun lojiji, laisi atunṣe" (Owe 29:1). Bẹẹ ni ọkàn Farao tubọ n sele ju bẹẹ lọ bi o ti n kọ̀ lati gba ipè awọn eniyan Ọlọrun.

**A Tẹnbẹlu Ọlọrun Nile**

Ọlọrun ni ki Mose sọ fun Farao nipa ajakalẹ-arun akọkọ ti yoo wá sori ilẹ. Gbogbo omi ni yoo di ẹjẹ, gbogbo ẹja ni yoo si kú. A ti kà pe awọn ara Egipti maa n bọ odo Nile nitori lori omi odo yii ni ounjẹ oojọ wọn sinmi le fun bibu omi rin ohun ọgbin wọn. Ọna ti eniyan le rin lori ilẹ ko i ti i pọ to nnkan, lori omi Nile yii si ni wọn maa n wọ ọkọ̀ lọ wọ ọkọ̀ bọ̀. Wọn gbẹ́ ilẹ lati la ọna ti omi le gbà ṣàn jade lati ara omi nla yii ki ọna omi le tun wà kaakiri si i. Gẹgẹ bi o ti jẹ pe ọpọlọpọ awọn ẹranko ni awọn ara Egipti maa n bọ, ẹja ni ounjẹ wọn pataki ju lọ. Nitori naa a le ri ohun ti o ṣẹlẹ nigba ti omi wọn di ẹjẹ ti awọn ẹja si kú. Ni ọna kin-in-ni, eyi tabuku si ọlọrun omi wọn. Ọlọrun wọn ko ha lagbara ju Ọlọrun awọn Heberu, ti i ṣe ẹrú. Ọlọrun Nile ti awọn ara Egipti n bọ ṣubu ni itiju niwaju ọpa ti Mose nà jade; omi naa bajẹ kó si dara fun lilo; awọn ẹja kú eyi si gba ounjẹ pataki kuro ni ẹnu awọn ara Egipti.

O dabi ẹni pe ọna kan wa ti wọn le fi ri omi daradara, nipa wíwa ihò lẹba odo naa. Awọn alalupayida naa si n gbiyanju lati ṣe afarawe iṣẹ-iyanu Mose ati Aarọni, ọ̀rọ ẹkọ yii wi pe, awọn pẹlu le sọ omi di ẹjẹ, nitori naa o ni lati jẹ pe iru kòtò kékèké bayii ni wọn lò. Wo o bi aayan wọn ti ṣe alainilari to nigba ti a fi wé awọn nnkan ti awọn eniyan Ọlọrun ṣe! Bi wọn ba n fẹ fi agbara wọn hàn o yẹ ki wọn mu arun naa kuro ki wọn si sọ omi naa di daradara; ṣugbọn wọn kò le ṣe eyi.

Kò tilẹ si ibakẹ́dun ninu ọkàn Farao fun ijiya awọn eniyan rẹ̀, nigba ti ọsẹ kan si dopin a mú arun naa kuro. Ṣugbọn omiran tun n bọ̀ wa.

**Ọ̀pọ̀lọ́**

Arun keji ni ti ọpọlọ. Eyi pẹlu tun jẹ ogun laaarin awọn ọlọrun ilẹ naa ati Ọlọrun otitọ Ẹni ti Mose ati Aarọni n ṣe aṣoju fun. Awọn ara Egipti ni ọlọrun kan ti o ni ori bi ti ọpọlọ, nitori naa wọn kò ni fẹ lati pa ọpọlọ rara.

Ṣugbọn nigba ti Ọlọrun rán ọpọlọ si ibi gbogbo lori ilẹ naa, awọn ara Egipti wa mọ pe awọn ọpọlọ le jẹ ohun miiran to bẹẹ. Wọn kò le dana sinu aaro wọn nitori awọn ọpọlọ yoo wà ninu rẹ; ọpọlọ yoo ko sinu iyẹfun ti wọn n pò nigba ti wọn ba n fẹ ṣe akara, awọn ọpọlọ alara tútù wọnyii yoo ti kún ori ibusun wọn nigba ti wọn ba n fẹ lati sùn. Ni akoko yii o ṣe e ṣe ki wọn bẹrẹ si ronu pe n jẹ ọpọlọ ha i ṣe ọlọrun. Ọlọrun ti wi pe, "Awọn ara Egipti yio si mọ̀ pe, emi li OLUWA" Awọn alalupayida pẹlu le mú ọpọlọ jade ṣugbọn wọn kò lagbara lati mu arun naa kuro.

O dabi ẹni pe arun yii yoo mu eso kan jade gẹgẹ bi a ti pinnu rẹ̀. Farao pe Mose ati Aarọni o si ni ki wọn bẹ Oluwa lati mu awọn ọpọlọ naa kuro, pe oun yoo si jẹ ki awọn eniyan naa lọ. Wò o bi inu Mose ti dun to pe awọn ti bori ninu ija naa! Ọkàn Farao rẹlẹ o si bẹ Mose fun aanu -- ṣugbọn wò o bi igba irẹ̀lẹ Farao ti kuro tó! Lẹsẹkẹsẹ ti a ti kó awọn oku ọpọlọ wọnyii lọ ni okiti okiti ni o pa ọkàn rẹ̀ dà. Ọpọlọpọ eniyan maa n gbadura si Ọlọrun nigba ti wọn ba wà ninu wahala; ṣugbọn lọgan ti igba rere ba tun de, wọn a gbagbe Ọlọrun. Gbogbo iwọnyi ni Ọlọrun n ṣakiyesi ati pe aanu Rẹ̀ ki yoo wa bẹẹ titi lae; O ti sọ pe Oun yoo rẹrin wọn nigba ti idamu wọn ba de.

**Idajọ Lai si Ikilọ**

Kò si ikilọ tẹlẹ ki Ọlọrun to rán arun ikẹta. Ọlọrun a kọkọ maa ba awọn eniyan sọrọ a si maa kilọ fun wọn nipa idajọ ti n bọ̀ wa, ṣugbọn bi wọn ba kọ̀ lati gbọ́, akoko naa yoo de ti yoo mu ki ajalu ojiji ṣubu lù wọ́n. Eyi maa n ṣẹlẹ ni igba ti wa yii. Nigba kan ẹni kan wá gbọ́ ọrọ Ọlọrun ninu ile-isin lọjọ kan, o si woye pe o yẹ ki oun fi ọkàn oun fun Ọlọrun, ṣugbọn o ni "Ki i ṣe ni alẹ yii" o si jade lọ ni alẹ ọjọ naa. Ki o to de ile ni o kú ninu jamba mọto. Nnkan kan naa ni o ṣẹlẹ si ọkunrin miiran ti kò gbọran nigba ti a pè é lati wá gbadura; ṣugbọn ọrẹ rẹ̀ kan fa a ni aṣọ sẹyin o si wi pe "Ma ṣe huwa aṣiwere" o si kọ ipe naa; ni alẹ ọjọ naa ni o rekọja si ayeraye lai ni Ọlọrun. Ẹmi Ọlọrun ki yoo fi igba gbogbo bá eniyan jà.

**Agbara Satani ni Iwọ̀n**

Iná ori ti o wá sori ilẹ naa, wá sori gbogbo eniyan ati gbogbo ẹranko. Wò bi wọn ti jiya to nigba ti awọn kokoro kékèké wọnyii bẹrẹ si i rìn lara wọn!

Awọn alalupayida wọn ti sọ ọpa wọn di ejo, wọn ti sọ omi di ẹjẹ, wọn si ti mu ọpọlọ jade sori ilẹ; ṣugbọn nigba ti wọn ṣe afarawe Mose lati mu ina-ori jade, wọn kò le ṣe e. Wọn jẹwọ pe lati ọdọ Ọlọrun otitọ ni iṣẹ́ ti Mose n ṣe ti jade wá, wọn kò si lagbara lati ṣe iru iṣẹ-iyanu bẹẹ. Satani ati awọn angẹli rẹ̀ kò le ṣe ju iwọn ti Oluwa ba fun wọn ni àye lati ṣe lọ.

Bi o tilẹ jẹ pe arun ti o wa sori awọn ara Egipti wọnyii jẹ eyi ti o buru lọpọlọpọ, igba kan n bọ̀ ti a o tú eyi ti o buru ju wọnyii lọ sori ayé. A kà nipa awọn arun ti o fẹrẹ jọ iru wọnyii ninu Iwe Ifihan, ṣugbọn dipo ti i ba fi wa sori awọn eniyan diẹ ni orilẹ-ède kan, a o mu ki wọn tubọ buru jai ju bẹẹ lọ, wọn o si wá sori gbogbo eniyan ti wọn ti yi pada kuro lọdọ Ọlọrun. A ni lati ba Oluwa rin timọtimọ nigba gbogbo, ki a ba le kà wá yẹ lati bọ ninu ohun buburu wọnni ti n bọ̀ wa sori ayé nigba Ipọnju Nla.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni arun mẹta akọkọ?
2. Ki ni ṣe ti a rán wọn jade?
3. Ki ni ṣe ti arun ti o kọlu odo Nile já si òfò nlá nlà to bẹẹ?
4. Njẹ awọn alalupayida le sọ omi di ẹjẹ, ki wọn si mu ọpọlọ wá sori ilẹ? Njẹ wọn lagbara lati mu awọn arun naa kuro?
5. Ki ni awọn alalupayida wí nigba ti wọn kò le mu ina-ori wá sori ilẹ?
6. Ki ni kikuna ti awọn alalupayida kuna lati mú ina-ori jade bi ti Mose kọ́ wa?